to Government, Lagos, Nigeria

From D. A. Obasa
Editor & Proprietor
"Yoruba News"
Ogunpa Rd
Ibadan


The

# Yoruba News

FOR GOD, THE KING AND THE PEOPLE.

VOL. 1. No. 23 IBADAN TUESDAY, JUNE 16. Price 3d. Weekly.



24 JUN 1925

# S. AGBAJE & CO.,

*General Merchants*

HEAD OFFICES:
GBAGI & AYEYE MARKET,
Ibadan, Nigeria.

Suppliers of:
Palm Kernels, Palm Oil, Cocoa, Maize, Rubber, Ivory &c, &c
also
MOTOR TRANSPORT SERVICE
Throughout the Western Provinces of Nigeria

## S. ABINUSAWA,

*Motor Mechanic,*

*Ogunpa Junction, Amunigun Mart, Ibadan.*

EXPERT REPAIRER
OF
Motor Cars and Lorries

Bring all your Sick Motors for curing.

CHARGES MODERATE.

## L. L. RICKETTS

*AGRICULTURIST.*
YEMETU STREET,
P. O. Box. 136. IBADAN.

Expert advice on the Agricultural Resources, Yoruba Land will be given to Amateur Planters on Application:—

Instructions with regards to Soil, Planting, Planting Seasons and the general routine of cultivation.

Selected Plants of Gbanja Kola are supplied on reasonable terms and various useful plants including fruit trees etc., etc., etc.

Also Instructions on the preparation, handling and storage of produce. An interview wil prove interesting.

Correspondence will becarefully attended to.

## White's Golden Female Tonic

Splendid Remedy for Female diseases such as - Barrenness, Weakness, Painful and Irregular Menstruation, Leucorrhea Whites Cramp Ovarian, Neuralgia. Inflammation of the Ovaries, A Tendency to Miscarriage etc etc.

Made and sold only by Victor White Esq
41, Offin Road Lagos.

*N.B.* Not obtainable elsewere.

## Gbogbonise fun Obinrin

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹdọ, Oyun, ti o ba fẹ bajẹ, ati orișirișị arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE

Boxing & Postage 2/-6 extra.

## White's Golden Male Tonic

"DOUBLE - STRENGTH"

Whenever a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs,

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic: "Doubl-Strength" is alculated to give full vigour to the man, and to remove al disease which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs

Made and sold only by Victor White Esq

*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road Lagos.*

N.B. Not obtainable elsewhere.

## Aremo fun Okunrin

Nigati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Șugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi daraspupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo Arun ti ki jẹ ki ọkunrin șe abiamọ.

N. B.-- O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loșoșu -- işẹ ti egbogi na nșe ni ara ko șe royin,

Price TEN SHILLINGS (10s)- per bottles

Boxing & Postage 2/6 extra.

PRINTING !

PRINTING ! !

**PRINTING ! ! !**

All Grades of

**ARTISTIC,**

**COMMERCIAL**

AND

*GENERAL JOB—PRINTING*

*ALSO*

*BOOK—BINDING,*

Neatly executed at Moderate Prices

AT

**THE ILARE PRESS**

Ajaba Square,

Ogunpa Road,

P. O. Box 60, IBADAN.

# Isaac F. Karunwi,

*Mechanical Engineer,*

# *Brookley Garage.*

*ONIREKE ROAD, IBADAN.*

Care P.O. Box 86.

Undertakes repairs to Motors.

Portable Engines & Machineries.

Typewriters, & Gramophone repairs a speciality.

EST. JAN. 1 1918.

# OWUYẸ.

## IṢẸ IYANU NLA ?

Ọkunrin ara Ile Olukosi ti a rohin ni ọsẹ ti o kọja pe o ṣe ara rẹ lese si wa bakannā ; a tilẹ gbọ pe oju ọgbẹ ara rẹ nā nsan diẹdiẹ nipa itọju awọn oniṣegun ti nwo ọkunrin na.

Iyanu nla ti o wa nibẹ ni pe ọkunrin nā nsọ fun awọn ti mba a wẹ ẹ pe ko dun oun rara.

Ọrọ na ko yeni si o. A fi i lọ awọn agba Dokita wa ti nwọn ti lọ Ilu Oibo. Ẹniti o ba fẹ, o le ri ẹni abami yi ni Ile Olukosi ni ilẹ yi loni.

Ẹran Ileya rọju pupọ ni ilẹ yi l'ọdun ni. Oibo kan lo fi Ọkọ-ilẹ ko agbo wa pitipiti lati Ilẹ Hausa, o si nta nwọn ni ọpọkuyọku ni Ọja Sabo. Nitori ko si wahala irin oju Ọna, gbogbo awọn agbo na yo daradara.

Apoti ni Oibo nā fi nru owo ẹran lọ si ile l' ojojumọ.

Aṣẹ̀ ọ̀wọ̀ ẹran pe ju Kòkó lọ ri ?

Ijọba gbe agogo sodẹ pe ki onile tun 'le se ; ki omi lilo ma di ijọ mẹta ninu ikoko nitori yanmuyanmu ; ki awọn enia mā lo asọ ti o mọ nigbagbogbo.

Ohuu ti o kù ni ṣiṣẹ ni ibẹwo ati itọju awọn Salanga gbogbo ni arin ilu ; ọrun buruku ti o nti inu Salanga wọnyi jade to lati da arun silẹ.

A mu eyi wa si iranti Ijọba. Ẹ ba wa ṣe o.

Anu ṣeni nipa ti Ajakalẹ arun ti nyọ nwọn lẹnu ni Abẹokuta nisisiyi. Ki Ọlọrun jọwọ dawọ ibinu rẹ duro ni arin awọn ọmọ iya wa nā

Orisirisi arun bi Ifọri, Igbona, Ẹhin didùn, ati amodi oniruru pẹlu iku ojiji pọ ni ilẹ yi ni saa yi. Ki Baba ṣọ wa o.

A ṣe idaro Ọgbẹni Adelenu Atẹwọlo gun, ti ile Amunigun, Ode Eko, ẹniti ọmọ rẹ obinrin Sabinah jaisi ni oru Satide tọhun, lẹhin amodi ọjọ mẹta.

Ki Oluwa fi Ọran mọ bẹ o, ki O si da awọn yoku si fun u.

Bẹni a ṣe idaro Ọgbẹni A. B. Lawanson, Ọga Iṣẹ Oju-Ọna Reluwe, ẹniti aya rẹ Tolani jaisi ni Tọsde ijẹta. Ki Baba tu Ọrẹ wa nā ninu.

A ki Ọgbẹni M. T Ṣitu Akọwe A & E. T. A. ti Iya rẹ jaisi ni alẹ ana.

Ẹ ku aṣẹhinde.

Anu ṣe ni lati tu ọfọ Ọgbẹni Lajide, Ọmọ Iyapọ Seriki, ọmọ Ibikunle,ti o jaisi ni awurọ yi. Ologbe yi ni ẹni pataki ninu awọn aburo Akinọla, Ẹkẹrin Balogun ti ndu ipo oloye ti ko si laipẹ yi. Lajide si ti na ọpọlọpọ owo si ipa didu oye nā ati si ipa isinku ti Ẹkẹrin.

A ki Oyetunde, Ladipọ ati awọn ọmọ Balogun Ẹ ku ọfọ.

Iyāfin Comfort Farẹmi sin ọmọ rẹ Omidan Elizabeth Gbemisọla Farẹmi ni iyawo fun Ọgbẹni Ezekiel Adeleke Babalọla, Tiṣa Ile-ẹkọ ti Ijọ Kutẹti ni Tọside ijarun.

## IKIRUN.

A ki ẹnyin ara Ikirun, Ẹ ku iṣẹ Ile oibo (Adajọ) ati ti Akọwe ti ẹ nkọ o, Ẹ si ku idele ti awọn ọmọ yin ti iṣẹ ti gbe lọ si ilu okere gbogbo. Ẹmi a r' ẹmi o !

A ngburo iṣẹ rere ti Saji-Mejọ Bamgbade nṣe ni ilu nā. Ori Ọba o gbe ọ o !

A ngburo iṣẹ rere ti Ọgbẹni E. P. da Alcantara nṣe ni ilu yi. Abusi Oluwa o

Anu ṣe ni lati gbọ iku Ọgbẹni James Oduoye, ẹniti a ko ri aisan tabi ailera kan ni ara rẹ tẹlẹ. O lọ si oko ni Satide, o si de niwọn agogo meje abọ ọjọ na ; o ta eknaọ fun Baba Ẹgbẹ. Afi iku rẹ ti a gbọ ni ọjọ keji May 10. Ki Baba ṣọ ni ni igba yi.

Isholarian Brotherhood School.

Bẹ na si ni awọn ọmọ Ile-ẹkọ ti awọn ọmọ lẹhin ti Ișọla Enikeji, a șe enia nsun orun agbara k'o tun kawọ soke? Wo, o yẹ yin o, jare. Ọkẹgẹ, o ku ișẹ o, amọdun wa șe ju yi o Așẹ!

Aiye Oibo dùn, Oyinmọmọ.

T' ọkunrin t' obinrin lo nfaga gbaga. Eyi ti a ti nșọ lọhun dun na bi o ba tun ri awọn ọmọ C. M. S. "Girl's High School" ti wọn tun nșe tiwọn, Hare!! Wa tun fẹrin s' ẹkẹ lẹkan si i Ki Ọlorun mà ran yin lọwọ,ju yi ni woyi amọdun o, Așẹ.

Bi Ile njo bi Ole nja ẹni ebi npa ki dakẹ

A kọ le șe alaidupẹ lọwọ awọn Ẹgbẹ "Young Ladies Club" ti obinrin akọwe makọmẹlẹ I. O. Ransome Kuti da silẹ ni warawere ti o de Ijẹbu-Ode yi na; awọn ni ko ma jẹ ki ebi șe kisa lara awọn enia ti nwọn lọ woran ọjọ na.

Amọ, "Ọfẹ kọ l'o nro o" Bi o ba ngbo atata Gẹsi ti obinrin yi nfun jade lẹnu ti o fi nta ọja nã, bi o di ogun pọnun s' apo ô na mẹwa ninu rẹ; ti awọn iyăfin Omidan B. Ọlaperi Adebọgun ati awọn ẹgbẹ rẹ iyoku nã nyan siwa sẹhin.

Owo lo mà ndun nibẹ o, ọrẹ, iyoku di ọsẹ ti inbọ lagbara Edumare.

Amọju ni i ba Ekùn Sãrẹ jẹ.

Ohun ti o mu ni pa irufẹ owe yi ni ohun kayefi ti a ri ni Ọjọ (Empire) Empaya, Bi a ti nfẹ bere si Ijo (Drilling) awọn ọmọde, ni Oyinbo D. O. pe Tișa ara lẹgnyin pe ki awọn ọmọ rẹ wa pitu ọrọ wọn; eyi ti a owi ti pẹ, awọn ọmọ rẹ ti da jade bi ọta ăgbá.

Warawere, Ọga wọn nã ti bẹrẹsi pe ișẹ fun wọn; ohun ti o wa șe wa ni Kayefi ni pe ọkunrin yi ti to kuro ni oju agbo, Irọ, ko kuro o! họwu!! tabi 'Ọna-ọfun iwọ nikan ni nwọn ntọ re Ọyọ"? Igbe lo nke: "Salute! 1.2!! A su wa!! la-koko ti ọgbẹni yi nikan lo ko ni șalai to ogbọn jẹgin.

Ẹ fi ohun ti ișe ti Kesari fun Kesari.

Ọ ta si ni leti fẹnrẹn pe Ajalorun Ọba Ifẹ-Ijẹbu, fi ẹnikan jẹ oye Balufẹ, Igbakeji ara rẹ, lai sọ fun Awujalẹ; șugbọn a tun gbọ pe Awujalẹ ti ranșẹ si wọn lati bi wọn ni idi Abajọ?

Iwe nkọ? Risiti rẹ da? Ẹ ma mũ nșo!

A gbọ pe awọn ọpa Ọba ti Ikorodu mu awọn akọwe gbowogbowo ati awọn Ọlọpa Ijẹbu diẹ nibiti nwọn gbe ngba owo ile kiri fun ẹsun pe nwọn kọja ala ilẹ Korodu pẹ Akarigbo ati awọn ẹsun jẹ owo pẹpẹpẹ.

Ọba Ọlugba'a ma șọ wa ninu irufẹ Iyọnu airotẹlẹ yi, amọ Ọlorun Ọba l' o nșeri afeyin pin ẹran loru.

Ọlọpa! Ọlọpa!! A bi șokoto pọnbe.

Aisi Ọlọpa ni awọn igun-igun ti o wa ni Porogun bu ibẹ ku pupọ; bi o nlọ lalẹ bi o ko mã ke onikẹkẹ ni yio tẹ ọ mọle-nigbati ko kuku tan ina nkọ?

Ọgọrọ tilẹ si ni awọn ti ko gba iwe aṣẹ (license) ti nwọn ngun u bi nwọn ti fẹ ni Porogun; eyi ma ku diẹ o. Ki ẹnyin agbaagba doiikodo si așa yi o.

Tușide ọjọ kẹrindinlọgbọn oșu ti o kọja, gbogbo awọn ọmọ Ile-ẹkọ lọ si Ile Ajẹlẹ ni Oke-Ọpa, lati lọ sire, awọn Ọba Awujalẹ, Olowu pẹlu awọn Igbimọ si lọ sibẹ.

Lẹhin nã ni Adajọ Agba fi ẹbun fun awọn ti nwọn șe daradara ninu ere Wọn si fun Olukulukku ile-ẹkọ ni owo lati lọ fi șe ariya.

A si dupẹ lọwọ Iyawo Olukọ Ile i-e giga ti ọkunrin, ti o șe gbogbo inkan lẹtoleto, ati awọn ọmọge na pẹlu.

## Iparoko.

Si Oniwe Irohin Yoruba, Ibadan.

Jọwọ masai fun mi ni aye bengan ninu iwe rẹ.

Nwọn ni "O jọ gàte, ko jọ gàte, o fi ese mejeji tiro;" o sebi owe o. Eniti o

## NAME.

A good name is rather to be chosen than great riches. Proverbs 22 ; 1·

By Ben N. Azikiwe.

My name is Joe yours is Jim,
His name is Tom, one's is Kim ;
Well then tell me the difference,
Asked a member in conference.

There is nothing in a name,
Ah ! Nothing worthwhile but fame ;
There is more than fame in it ;
What's in a *name* then ? *On dit.*

The prisoner, his *name* is gone,
But still he fights till its done,
For they that lose this fine pearl,
Regret from peasant to Earl.

Then *name* is of importance,
But *good name*, significance,
Why not then strive to maintain-
*Good name* the golden fountain ;

*Good name* is dear to ignaves,
It is dearer to all braves
Though ignaves and braves be true,
Yet they pursue *good name* through.

My compatriots and lovers,
Now seek *good name* like livers
Who live for good and justice
For all that's pure and peace.

## ỌWỌ.

Mr J. O. Bayọde the Court Clerk has been transferred to Ikarẹ since the 30th ultimo. He will be missed much by his friends, his neighbours, (the Government teachers and the Postmaster,) and towns people

Mr Bayọde's reliever, Mr. J. D. Adejugbe, one of the sons of the Agoga of Akurẹ, came on Friday the 29th ultimo. He is a stranger here, and a great responsibility rests on him.

We wish both officials success in their new spheres of work.

While bidding Mr. Bayọde : Au revoir ! We tender our Hearty Welcome to Mr Adejugbe.

## SI ONIWE "IROHIN YORUBA"

Mo bẹ yin lọpọlọpọ ki ẹ masai fun mi ni aye diẹ lati sọrọ diẹ yi.

Awa ti gbọ firinùrin pe Ẹni-ọwọ J. Mckay tun mbọ wa si Osogbo pẹ diẹ ; ṣugbọn nigbati emi kọkọ gbọ, ngko gbagbọ, afi igbati mo ngbọ ọrọ nā lẹnu awọn agbagba, ọkan mi wa ngbagbọ ; mo ni, bi araiye ko ba ri nwọn ki wi. Lẹhin nā, Alufa wa Ẹni-ọwọ Ṣodipẹ tun fi lọ ni Ṣọṣi pe Alabojuto Ijọ wa tun mbọwa o, nigbayi ni o to wa da mi loju kedere.

• Nigbati o di ọjọ ọsẹ ti a lọ si Ile Ọlọrun fun Isin (27/4/25) ni Alufa tun sọ pe, titi ijọ mẹrin a ni lati lọ pade rẹ ni idikọ. Tōtọtōtọ na, nigbati o di ijọ kẹrin ọsẹ (29/4/25) mo lọ si Idi-ọkọ, ṣugbọn ohun ti o ya mi lẹnu ju nibẹ nipe "Owẹ ni a pe inkan yi, o si l' arọ ninu" Awọn obinrin da ẹwu kọkan ti nwọn ya sọtọ fun pipade Alabojuto wa yi.

Nwọn lọ si Idkọ pẹlu Ilu ati Ijo ; gọngọ sọ l' ọjọ nā. Ọna Idikọ ko gba ẹsẹ ; bi Abẹrẹ bọ ko le kanlẹ lọjọ ti a nwi yi. Ani awọn ọmọ Ile-ẹkọ ti Ologun Igbala (Salvation Army) lọ si idikọ na pẹlu Ilu oibọ, fere ati orin ti o dun pupọ. Awọn na si fi tayọtayọ pade Alabojuto wa yi. A dupẹ lọwọ ọga wọn ; nwọn se, nwọn ku aṣeyẹ o, bẹ̄bẹ la o ma ri o.

Gbogbo wa ba Alabojuto wa yi kẹyẹ de ile rẹ, inu ẹnikẹni, ti ọmọde ti agba wa lo dun lọpọlọpọ lati tun ri i lẹkan si i A dupẹ lọwọ Ọlọrun fun eyi; inu wa si tun dun nigbati a tun gbọ pe o gba oye si oye rẹ, oye Olori alufa (Archdeacon).

Oye a pe lori o. Iwaju ni ọla yio mā lọ o. a ki ọ Alabojuto Mo fẹ ki gbogbo ẹniti yio ka Iwe yi ti ẹ jẹ ibilẹ Oṣogbo ki o mura lati ja mi ni iyan fun ọrọ kekere ti mo lẹ sọ yi.

Ẹni-Ọwọ Mckay jẹ ẹnikini ti o kọ mu Igbagbọ de ilu Oṣogbo, ninu awọn oibo *Missionary* ; akoko na si le pupọ (ko jọ igbati Obẹ wa tutu ti adamu wa nfā à la yi) o se ọpọlọpọ wahala ati lālā, ninu igbo, ni irin ojo, ati ni ọpọlọpọ ohun miran nipati emi.

*Koi ti pari*

## THE YORUBA NEWS.

*Editor & Proprietor:—*
D. A. ỌBASA,
Office—AJABA SQUARE, OGUNPA ROAD.
P. O. OX 60, BA DAN.

*Subscriptions payable in Advance*
Ibadan 1s, per annum. 14s Post Free.—
Cheques and Orders should be crossed and forwarded to the Editor.
Advertising rates &c. on application


## Publications Received.

THE Annual Report on the Government Printing Department for 1924 is worth studying by all private Printing Offices in Lagos and Nigeria generally. The quantity of printed matters yearly turned out of this department is simply wonderful. There were 2.970.896 Forms and 302.558 Books printed in 1924, at a cost of £30.000. This is only made possible by the quantity of printing materials which enabled the department to keep 1952 Formes standing without interfering with the other jobs numbering 742 in 1924.

It would be a happy day for us in Nigeria when we can combine to put up such large industrial establishments to be worked on co-operative basis.

We congratulate the Government Printer and staff for the smooth working of the department.

The Annual Report by the Police Magistrates for 1924 is very interesting from many points of view. It reveals the fact that the morality of the people is steadily improving and that crime is becoming less prevalent at Lagos and Calaber.

The slight increase at Ebute-metta was we are glad to note, due to numerous prosecutions under the Town Council Regulations and not criminal proceedings. It shows the settled state of the country and the influence of education in the life


ASAN SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ

| | Ibadan | Ilu Ẹhin Odi. |
|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/ | 14/ |
| Oṣu mẹfa | 6/ | 7/ |

Ẹ fi owo pẹlu *Letter* ranṣẹ si *Editor*


of the people for which we are thankful to the British Government.

A copy of the Annual Report on the Public Works Departments for 1924, was received from the Government Printer with thanks. This will be dealt with later.

We have also received from the publishers with thanks, a copy of "Yoruba Phrase Book" with phonetic spelling by H. L. Ward-Price, Esq., Political Officer, Nigeria.

The author, who was a District Officer in this Province has produced a really useful book invaluable to all literate non-Yorubas in acquiring a knowledge of the language. The phonetic spelling adopted is a decided advantage to this class of learners who generally get confused with the pronounciation of the existing method of writing the language.

We recommend this book to all Europeans-Officials and mercantile--who will find it a great help in their efforts to learn and use the language. The book obtainable at the C.M.S. Bookshop.

We have received with thanks a copy of "The Spokesman" March Number, from Mr. Ladipo Ṣolanke of London University through Mr. F. Olawale Lucas of 17. Alli Street Lagos.

This paper is edited by Mr. Thomas W. Anderson and published monthly at 119 West 136th Street New York at $2.00 p.a. post free.

"It is one of the most powerful and instructive organs among our brethren in America. It is particulary enthusiastic to allow through its columns an oppor-

tunity for the exchange of views between the Negro at home and the Negro abroad with a view to arriving at some sane and useful understanding for a happy and effective unity and co-operation for the race progress in the right and proper lines."

Mr. Ṣolanke is prepared to supply sample copies on application.

## News & Notes.

Mr. E. V. Watson of the Local Treasury left for Lagos on Monday the 15th instant on transfer

A Send-off Dance in his honour was given by a Committee of Gentlemen in the Ibadan Billiard Saloon on Friday night the 12th instant. He will be missed by his many friends in this town.

Wishing Mr. Watson every success in his new sphere of labour.

Welcome to Mr. S. T. Odẹrinde Ladega who relieved Mr. Watson at the Local Treasury, Township Court.

His Excellency, F. M. Baddeley, Esqr., C. M.G., the Acting Governor, arrived here early this morning. After inspecting the Public Offices, His Excellency left for Ọyọ in the afternoon.

It is now 25 days since the Bale of Ibadan went to Ọyọ and is still away.

The Balogun, the Ọtun Bale, Ọtun Balogun and other chiefs of Ibadan went to Ọyọ last Saturday and returned the same day.

We continue to hear all sorts of urgly rumours from Ọyọ about the Balẹ and chiefs.

We congratulate the Revd. and Mrs. M. C. Adeyẹmi, of the Ondo Public Boys' High School, upon the arrival of their new baby on the 29th ultimo.

We learnt the authorities are providing a public Cemetry behind the Race Course for the use of the intelligent members of the Community.

Telephone Lines have been extended in to the town as far as Alafia House, Ayẹyẹ Market, via Idikan Street.

We understand a section of the Water Supply scheme for Ibadan is being taken in hand, beginning with Old Residency area.

Corpus Christi Festival celebrated here last Sunday was attended by large crowds of people. Gbagi and Catholic Streets were gaily decorated for the occasion.

Our Congratulations to the Revd. Father Freisse the Superior, for the success of the service.

### MINNA NEWS.

Congratulations to Mr. G. W. Graves upon the arrival of a male child, on the 8th instant.

## ILEṢA.

Ni Ṣọnde ti gbogbo enia joko si Ṣọṣi ni ọmọkunrin kan nja ẹṣin bọ firifi ni oju opopo, afi gbi-i-i ti ẹṣin la a mọlẹ ni ọkankan Ṣọṣi papa, ti ẹṣin nā si tẹ awe nā ni ikun mọlẹ daradara.

Ifarapa ko to itiju niwaju gbogbo ilu ti nwọn fẹrẹ pesẹ sibẹ tan fun Isin pataki kan ni ọjọ na

Ko yẹ ki onigbagbọ mā ja ẹṣin kiri ni Ọjọ-isimi, papa ni akoko Isin:-

## KADUNA.

Ọgbẹni E. A. Adeyinka, Akọwe Ọfisi Ọlọpa, lọ si Kano fun iṣẹ adele Akọwe wọn ti o gba aye isimi oṣu kan. A ni ireti pe yio si tun pada bọ si aye rẹ laipẹ.

## Thanks for Sympathy.

Mr. A. B. Lawanson; Railway Contractor on behalf of himself and family, tenders his sincere thanks to all kind friends and well-wishers who by personal calls, letters and telegrams expressed sympathy with him for the loss by death of his beloved wife Madam Tọlani, who was translated to internity on the 12th instant.

R. I. P.

pe ara rẹ ni "Baba" kole se alai l'ọmọ lẹhin. Awa ọmọ 'Baba' ri bi gbogbo nyin ti nda a lohun ninu iwe irohin yi fun itan ti "Ekiti ko si labẹ Ilesa." O to akoko fun wa lati kin "Baba" wa lẹhin. Ọpọlọpọ ọpẹ lo yẹ Ọgbẹni "Agbọ-nu-bini" fun kinkin ti o kin "Baba" wa lẹhin ninu iwe yi ti 10.3.25, ni oju iwe kini.

Pẹlẹ o "Ai" ti Eko. Mo fẹ ki o mọ pe "Baba" ko ja fun ara rẹ nikan ṣugbọn eviti o kan gbogbo wa l'o nsọ. O daju pe o ko le mọ itan Ọyọ ju "Baba" nitoripe iwọ ki iṣe "Ai" ti Ọyọ.

Onibẹwo Ilesa, rọra o! Ninu ẹṣẹ keji iwe rẹ ti 31 3 25, o so pe "Nigbati Ewi tilẹ nje "Ọsọkọ Ekiti sọkọ Akoko" ilu wo ni Ado da ko ri?" Ṣe iwọ na mọ oye ilu ti Ilesa da ko ri? Gẹgẹbi o ti wipe irẹpọ ni awọn Ekiti ati Ilesa ti wa lailai bẹ na lo yẹ ki nwọn o wa nisisiyi. Iwọ "Onibẹwo Ilesa" to pe "Baba" ni "Adijasilẹ ta kete" mo fẹ ki o mọ pe oruko yi ko yẹ "Baba" rara; ẹniti oruko yi yẹ ni eniti o ṣe "Ilesa Calender" ti 1925 ti o pe Ọwa ni "Ese" (Olegbo) ti o si pe gbogbo Ekiti ni "Ekute." Ẹnikan ti o jẹ ọmọ Ekiti kọwe sinu iwe irohin Yoruba yi lati kilọ fun u tori ọjọ miran; o si bi i ni ibere diẹ, ṣugbọn ko dahun. Mo ro pe o gba ẹbi rẹ, nitori owe oibo kan wipe "Silence means consent." E o ri ọrọ ọmọ Ekiti na ka ninu iwe irohin ti Jan. 20-27 25 ni oju iwe kẹjọ. "Majẹko-bajẹ" ti iwe irohin 17.2 25. oju iwe kẹta, ṣe o wa ri nisisiyi pe "Bi eti ko gbọ yinkin inu ki i bajẹ?"

Mo dupẹ lọwọ rẹ Edito.

Koi ti pari. Emi Ọmọ "Baba."

### IJỌ EBENEZER NṢE EREE

A ranṣẹ si mi lojiji lati wa woran kan ni Ile-isin Ọlọrun ti "Ebenezer" ti Ijọ Ọmọbilẹ ni Sọnde ti o pari esu ti o koja mo si kọ tẹlẹ ninu Ile isin yi. Gbogbo eoia si nya wa bi omi. Mo bere pe: kini nwọn tilẹ pe mi si? Ekeji mi si sọ fun mi pe "Eniti a ngbe iyawo bọ wa ..."

ki inọga.

Ni agogo mẹta abọ ọsan ni awọn Ẹgbẹ "Gospel Band" ati "Morning Star" ti Ijọ *Ebenezer* yi bẹrẹ ere nla kan labẹ Alaga Ọgbẹni James Taiwo, anọwo bi ẹlẹda ati awọn Isọngbe rẹ awọn Ọgbẹni J. O. Lasole, I. F. Karunwi, E. A. Lapitẹ, ati J. Ogunniga ati awọn Iyafin meji G. T. Obigbẹsan a-fi-dudu-sọla, ati Janet F. Taiwo afun-bi-eyin.

Nwọn si ti se eto ohun gbogbo silẹ kinikini; gbogbo awọn ti nwọn kọ orin ninu ere yi to ogoji enia t'ọkunrin t'obirin. Duru ndun bi ẹnipe ki a ma tilẹ fọwọ kan a mọ. Kosẹ ni i; bi ẹni so ogoji mọ ogọjọ ni, gbogbo rẹ nṣe rẹmu Orin adakọ ti o wa ninu rẹ jẹ "Atariẹ ajanaku, ti kiṣe ẹru ọmọde" ni awọn ti o so ulwon.

1 Mas. Oloyede ati Karunwi. Song: Hear O Saviour.
2 Mas. Johnson, Recitation.
3 Mas. Oloyede ati Miss. Mọlake Song Hail Our Brotherhood.
4 Mr Christopher: Song Is My Name Written There?
5 Mas Gbemi Recitation.
6 Mr. Festus Yoruba Song: Ẹ rọra mọ an wa wo Irawo.
7 Donation by 4 specially Elected Ladies
8 Miss A Glover Song Ẹnyin Ijọ Ebenezer
9 ,, Kudaisi Song: Remember me O Mighty One!
10 Mas. Ṣomoye Recitation
11 Miss Kudaisi Song Speeding Away
12 ,, Yewande Oshodi Song There 'll be joy.
13 ,, A. Glover Song Oluwa to mbaṣiri
14 ,, Yewande Oshodi Song: O ba kan f' ogun wẹri.
15 Mr Christopher & others Song F'alafia Rẹ fun wa.
16 Miss Esther & others Song The day is dying in the West.

Ninu awọn wọnyi a le sọ pe bi Ọgbẹni Christopher ati awọn Omidan A Glover, Kudaisi ati Yewande Oshodi ba ri ọbẹ nwọn yio jẹ Ẹkọ: —owe.

Alakoso gbogbo orin ati eto ni Ọgbẹni E. A. Allen, Aluduru Ṣọṣi Ebenezer, lati gbiyanju lati rohin tabi lati juwe bi wọn ti ṣe ere yi si dabi ẹni wipe oluwarẹ pa 'okuta si i" irohin ko to afojubata 'Owo ti nwọn da nibẹ jẹ £2-1-0 awọn ọmọ Ẹgbẹ meji yi yọda owo na fun kikọ Ile Ọlọrun titun ti nwọn fẹ gbe naro. Pẹ bẹ ni ki a ma ri o.

1.8.25. Adeọla.

*Continue from our last Numb.*

**EMPIRE DAY, ỌWỌ 1925.**

The following were the other events,

High Jump (Snrs.) All 3 places won by C.M.S.
" " (Jnrs.) 1st. by Govt. 2nd, by C.M.S. 1st. by Ipelo last 3 place bracketed
Pole Jump (Snrs) 1st by Govt. 2nd by C.M.S. the 3rd bracketed
(Jnrs) 1st & 2nd by Govt. 3rd, by C.M.S.
[illegible]ml Race (Senrs) All 3 won by C.M.S.
" " (Jurs) 1st & 2nd, by C.M.S. 3rd place won by Govt
Infants' Race 1st & 3rd, by Govt. 2nd, by C·M.S.
Blind Donkey Race 1st & 2nd, C.M.S. 3rd place won by Govt.
[T]read and Needle Race (Girls) All 2 places won by C.M.S.
[E]gg and Spoon Race Girls, by C.M.S.
[T]he last of all was Tug-of-war, another [t]eam game, was won by the C.M.S.

## IGBEYAWO IBADAN.

Alagba/

Inu wa yio dun bi ẹ ba le fi Iwe kekere yi ṣe wa ni ōre ninu Irohin ti yio [m]a jade yi ; nipa Iyawo tabi ana ṣiṣe [n]Ilu Ibadan, ati owo ti a ngba nigbati [a]irin nā tabi Iyawo na ba salọ-yala ki [o] to de ile, tabi gẹrẹ ti a ba mū u de ile [t]i ti wọn ba sin i fun ọkọ rẹ.

Igba gbogbo ni awọn Ijọba nsọrọ si ti [a]wọn Alarede ti wọn ba kọ ọkọ silẹ, nitori pe o kọja labẹ ofin Gẹsi (Ki nwọn to mu arede). Ṣugbọn awa bi alayapupọ (Polygamists) a ko le ṣalai wò bi wọn ti ngbowo lọwọ wa si, ati iye ti a [n]gba pada, bi o ba fi wa silẹ tan ; lẹsẹkanna, a ko le ṣalai boju wo ẹhin, ki a si wo iru ofin ti awọn ọmọ iya wa nlo ni Abẹokuta fun iru inkan kanna ti o nṣe wa nihin, nigbati o ba ri bẹ fun wọn lọhun. A fẹ ki nwọn ba ni wo bi Inawo ti a nṣe, tabi ana Iyawo ni ilẹ yi ati Iye ti o mbọ si ti pọ to. O tilẹ jubẹlọ ti a ba wo o daradara.

| Iṣiṣẹ KINI. | £. | s | d |
|---|---|---|---|
| Owo Iya | 1 | - | - |
| „ Baba | 1 | - | - |
| „ Ọmọ | 1 | - | - |
| „ Bāle | - | 10 | - |
| „ Obirin Ile | - | 5 | - |
| „ Ọmọkunrin | - | 5 | - |
| „ Ọmọ Osu | - | 5 | - |
| | 4 | 5 | - |

| Iṣiṣẹ KEJI | £ | s | d |
|---|---|---|---|
| Owo Isanlelori | 5 | - | - |
| „ Iyinfa at Ipayẹrun | 2 | 10 | - |
| „ Bamiṣē | - | 10 | - |
| „ Ibọlọwọ | 7 | 10 | - |
| „ Abẹ-Ẹni | - | 10 | - |
| „ Ipalẹmọ | 1 | - | - |
| „ Alarinà | - | 10 | - |
| „ Idajọ | - | 10 | - |
| | £18 | - | - |

| Iṣiṣẹ KẸTA | £ | s | d |
|---|---|---|---|
| Owo Ikònà | - | 5 | - |
| „ Ifọwọrọgi àjà | - | 5 | - |
| „ Iwẹ Iyawo | - | 5 | - |
| „ Ọmọ Iyawo | - | 2 | 6 |
| „ Ibale | - | 10 | - |
| | £1 | 7 | 6 |

| | | | |
|---|---|---|---|
| Apapọ gbogbo rẹ jẹ | £23 | 12 | 6 |

Lẹhin gbogbo eyi, oriṣiriṣi Inawo ile ana wẹwẹwẹ miran, tani ko mọ eyi ? Ki a to ṣẹṣẹ wa ṣe Iyawo pẹlu inawo ọpọlọpọ, a si sa tọ ẹlomiran lọ wọn a ni ki a wa gba pọun mejila ābọ £12 10 0.

Ede rē o

Ara Ibadan.

Owo ịọbẹ-Oloropò, Onilu, jijẹ, mimu fun awọn Ẹgbẹ Iyawo ati ti ọkọnkọ ? Lai ti ka oriṣiriṣi Inọwo ọdọdun bi. Iṣu, Adiẹ, Epo, Igi, ati bẹbẹ.

Ed. Yor: News

# THE NIGERIA LABOUR CORPORATION

## ẸGBẸ AGBAJỌ AWỌN OṢIṢẸ.

Ẹgbẹ yi ti daraba, o diji, ò ti dohun akunlẹbọ. Oṣiṣẹ ti ko i ti wọ, ko mo odo ti oun ndọra si. Ọmọ Ẹgbẹ yi ti le ni (500) ẹdẹgbẹta A ko kọ ẹnikan, iba ṣe akọwe, tabi lebira, Ṣile kan 1/- la fi nwọ, ṣile mẹwa (10/-) ni owo dida ọdọdun, asansilẹ ni o, a si le da san lẹmeji tabi jubẹlọ.

AWỌN ẸGBẸ YI NI A TI DASILẸ LABẸ AKOSO YI:—

| | |
|---|---|
| **The Native Nurses Union** | (Ẹgbẹ Olutọju Alarun |
| **African Steamer Association** | (Ẹgbẹ Oniṣẹ ọkọ oju omi) |
| **The Post & Linesmen Union** | (Ẹgbẹ akowekiri ati Oniwaya) |
| **The African Pensioners Union** | (Ẹgbẹ Oniṣẹ Ọba to ti simi) |
| **The African Police Defence Club** | (Ẹgbẹ akọya fun Olọpa) |
| **The Motor Drivers Association** | (Ẹgbẹ Awamọto) |
| **The Engine-Drivers Union** | (Ẹgbẹ Awakọ Ilẹ) |
| **The Sanitary Inspectors & Vaccinators Union** | (Ẹgbẹ Wole-wole ati Bupabupa) |
| **The Carpenters & Joiners Union** | (Ẹgbẹ awọn Kafinta) |
| **The Painters Association** | (Ẹgbẹ akun-ọda) |
| **The Bricklayers Union** | (Ẹgbẹ mọlemọle) |
| **The Printers & Compositors Union** | (Ẹgbẹ awọn Atẹwe) |
| **The Farm Labourers Union** | (Ẹgbẹ awọn Alagbaro) |
| **The Common Carriers Union** | (Ẹgbẹ Alaru Ita) |
| **The Casual Labourers Union** | (Ẹgbẹ Alagbaṣe) |

Ewo ni tirẹ, ẹnikeji? O ba wa nile, o ba wa nidalẹ, sa fi orukọ rẹ, iṣẹ ti o nṣe, ẹniti o nsin, ibi ti o ngbe ati owo Ẹgbẹ rańṣẹ si akọwe

The Secretary,
Nigeria Labour Corporation
Iron House 4, Tinubu Street
Box 251, Lagos, Nigeria.

A ni Office ni Ebute Meta, ni Denton Street, l' Ẹhin Ọgba Loco Railway.

GBOGBO OṢIṢẸ, E WA!

# FOR SALE.

INDIANA LORRY

## L 1107

**Quite New**

Only Three Months in use

Apply Editor

---

# TO LET

---

# HUDSON COLE,

*Builder and Contractor.*

***Undertakes & executes all kind of BUILDINGS & OTHER CONTRACTS in any part of Nigeria***

***Plans & Estimates Prepared***

**Lagos Address:**

40.A, JOSEPH STREET.

**Ibadan Address:**

GBAGI STREET IDDO GATE.

# OIBO ALAGBON

Ile Owo Ekini ni ile yi ti şi Ile-Qja Titun ti nwọn şeşe kọ si OBDE IDO, IBADAN. Orişirişi Aşọ, Işọ̀şọ Wò-siwósì, Awo Abọmafọ, Ohun-Elo onirin oniruru ati Qpọ Orişi Qja miran lo mbẹ nibẹ

## WA WORAN!!

---

**Ibadan Billiard Saloon**

Ido Gate, Gbagi, Ibadan.

Oppesite P. Z. & co.,

GAMES:

Billiard, Skittles, Dominoes, Draught, Ludo, Cards and Syrian Draught also Dancing

EXCELLENT MUSIC PROVIDED.

**A Bar is attached for the convenience of visitors.**

***M. K. Assaf,***

Manager & Commission Agent.

---

MUSTAFA ADENRAN

NI

nişọna Atata ni popo

Bode Qna Ido,

IBADAN

Agbada to jire, Ẹwu saro ti gba jumọ, Ẹwu Qyala ati wọtẹlẹ ati Şokoto ti o şe rẹgi nibẹ lo pin si

**IROHIN KO TO AFOJUBA**

# IṢE OLODUMARE DISPENSARY

Joshua O. Ade: Craig.
*Manager & Proprietor.*



BRANCHES AT
AGBẸNI OṢOGBO
& LAGOS.

## KINI TO ALAFIA ?

Egbogi fun oriṣiriṣi aisan wọnyi ṣeṣẹ de si Ile Egbogi ti a npe ni IṢẸ OLODUMARE ni Opopo Gbagi:—

Egbogi, Oyi, Iba, Ikọ, Atperi, Ọrẹrẹ, Arinka, Lakuregbe, Sobia, Jẹdijẹdi, Akokoro Akandan, Oju, Eti, Otutu, Ẹhin, Osi, Egbogi titọju, Aboyun, titọju Ọmọ ọwọ, Arun kiniṣa, Ẹda, Inorun, oriṣiriṣi Egbogi fun ailera Obinrin.

Egbogi fun ilera Ọmọkunrin, Egbogi fun arun-karun lara Ọmọkunrin ko ma ye ọ. Ya nibẹ ki o mu tirẹ, o le ri Alabojuto laṣiri bi o fẹ. Ki Olowo wa, ki Alawin wa, araisan ni ko dara. Iwọ ko tilẹ gbọ oruko ilẹ ni ndan? "IṢẸ OLODUMARE."



# ANGLO-COLONIAL TRADING CORPORATION, LIMITED.

Broad Street, Lagos, &
OGUNPA, GBAG STREET, IBADAN
The Cheapest and Best House for
**NEW PROVSONS**
Wines, Spirits, Beer etc. &
ALSO
Cotton and Sundry Goods



# E. T. SOLOLA,

*General Merchant*

HEAD OFFICE:
39, SERIKI STREET,
P. O. Box, 407.
LAGOS, NIGERIA.

**Dealer in various articles suitable for different kinds of Market in Nigeria. Matchets and lay Pipes always in stock**

**Enamelwares,
Crockery
Gunpowder,
Hardware,
and other articles are obtainable at surprisingly low prices**

**COME ONE, COME ALL**

SHOWROOMS: 3 Martins Street Lagos
Ajaba Square, Ogunpa Road, IBADAN.


Printed and Published by D. A. OBASA at The Ilare Press, Ogunpa Road Ibadan